# ẸKỌ ÈDÈ YORÙBÁ FÚN ILÉ-ẸKỌ OLÙKỌNI ÀGBÀ

## ÀKÓJỌPỌ̀ ẸKỌ ÈDÈ YORÙBÁ ( ATỌ́NÀ AKẸ́KỌ̀Ọ́ )

## ẸKA ẸKỌ ÈDÈ YORÙBÁ

FEDERAL COLLEGE OF EDUCATION
ÒSÍẸ̀LẸ̀ - ABẸ́ÒKÚTA
ÌPÍNLẸ̀ ÒGÙN

Alàgbà Túnjí Ọ̀pádọ̀tun (Olótùú)

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# ẸKỌ́ ÈDÈ YORÙBÁ FÚN ILÉ-ẸKỌ́ OLÙKỌ́NI ÀGBÀ

ÀKÓJỌPỌ̀ ẸKỌ́ ÈDÈ YORÙBÁ
(ATỌ́NÀ AKẸ́KỌ̀Ọ́)

Àlàgbà Túnjí Ọ̀pádọ̀tùn (OLÓTÙÚ)
A. D. 2000

ẸKA-ẸKỌ́ ÈDÈ YORÙBÁ
FEDERAL COLLEGE OF EDUCATION
Ọ̀ṢÍẸLẸ̀ - ABẸ́ÒKÚTA
ÌPÍNLẸ̀ ÒGÙN.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

*Ilé iṣẹ́ ti o gbé iwé yií jàde ni*
**VISUAL RESOURCES PUBLISHERS**
P. O. Box 4107
Ibara, Abeokuta

*Ni ọdún 2000 ni a kọ́kọ́ gbé ìwé yií jàde.*

Ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ da ohunkòhun kọ làti inú ìwé yií ní Ọ̀nàkọnà yàtọ̀ fún ìlò ara rẹ nikan láìgba aṣẹ fún ṣiṣe bẹ́ẹ̀ láti ọwọ́ ilé iṣẹ́ aṣèwétà tó gbé e jáde Visual Resources Publishers; P. O. Box 4107, Ibara Abeokuta.

©
ADÉBÍYÌ A. ADÉKẸ́MI
FÁJẸ́NYỌ̀, S. ADÉRẸ̀MÍ
SÓLÀJÀ, FỌLÁKẸ́ S.
ADÉYÍNKÁ, ADÉYẸMÍ A.
SÓDÍPẸ̀, NURUDEEN O.
SÀNYÀ, AYỌ̀MÍDÉ G.
ÌRÓKÒTỌ́LÁ, P. KẸ́HÌNDÉ
ADÉLÉKÉ, DÚRÓTOYÈ A.

ISBN 978-34467-1-1

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# ÀTẸ ÀKÓÓNÚ


| | | Ojú -Ìwé |
|---|---|---|
| ÀWỌN AKÓPA: | | ii |
| ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ: | | iii |
| ÀTẸ ÀKÓÓNÚ: | | iv |
| ÌDÚPẸ́: | | |
| Orí kìn-ín-ní: | Ìdàgbàsókè Àti Àkọtọ́ Èdè Yorùbá: Kẹ́mi Adébíyí | 01 - 18 |
| Orí kejì: | Fónẹ́tíkì Àti Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá: Nurudeen Ṣódípẹ̀ | 19 - 38 |
| Orí Kẹta: | Ìlò Èdè Yorùbá: Fájẹ́ǹyọ̀ Adérẹ̀mí | 39 - 62 |
| Orí Kẹrin: | Àròkọ Àti Àkàyé Èdè Yorùbá: Ayọ̀mídé Sànyà | 63 - 84 |
| Orí karùn-ún: | Gírámà Èdè Yorùbá: Fọlákẹ́ Ṣólàjà. | 85 - 125 |
| Orí Kẹfà: | Mofọ́lọ́jì Èdè Yorùbá: Kẹ́hìndé Ìrókòtọ́lá | 126 - 135 |
| Orí Keje: | Ẹ̀ka Èdè Yorùbá: Yẹmí Adéyínká. | 136 - 155 |
| Orí Kẹjọ: | Ẹ̀kọ́ Ìtumọ̀ Èdè Yorùbá: Dúró Adélékè | 156 - 175 |


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# ẸKA ÈDÈ YORÙBÁ

YẸMÍ ADÉYÍŃKÁ

## ÈRÒŃGBÀ

Léyìn ẹ̀kọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́:.

(i) yóò lè ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ohun tí èdè jẹ́ àti àbùdá àdáni èdè.

(ii) yóò lè sọ̀rọ̀ lórí èdè Yorùbá àti bí tí a ti lè rí àwọn ẹ̀yà yìí ní àgbáyé.

(iii) gbọ́dọ̀ lè sọ̀rọ̀ lórí ẹka èdè Yorùbá, ìyàtọ̀ tí ó wà ní ààrin ẹka èdè àti Yorùbá àjùmọ̀lò àti láàrin àwọn ìpín ẹ̀yà Yorùbá.

(iv) gbọ́dọ̀ lè ṣe àlàyé lórí bí a ṣe ń dá ẹka èdè Yorùbá mọ̀.

(v) yóò lè tọ́ka sí ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìdí tí ẹka èdè Yorùbá ṣe pín yẹlẹyẹlẹ.

(vi) gbọ́dọ̀ lè ṣe àlàyé tí ó kún lórí àrànmọ́ àti àǹkóò fáwẹ́lì.

## KÍN NI ÈDÈ?

Èdè ni a lè pè ní ìlànà tí ẹ̀yà ènìyàn kan ń gbà láti fi èrò inú wọn hàn, yálà nípa kíkọ èrò náà sílẹ̀ tàbí nípa sísọ ọ́ jáde lẹ́nu, ọ̀nà tí ó fi lè yé gbogbo ènìyàn tí ó ń lo ìlànà náà.

Ní ọ̀nà mìíràn, a lè pe èdè ní ìró tàbí àmì tí àwọn ènìyàn kan fi ìmọ̀ ṣọ̀kan láti máa fi bá ara wọn sọ̀rọ̀. Ó jẹ́ ọ̀nà tí ènìyàn ń gbà sọ ọ̀rọ̀ sí ara wọn èyí tí wọ́n lè ṣe nípa lílo àmì lásán bíi fífi ọwọ́, ojú, orí, ẹsẹ̀ tàbí àwọn ẹ̀yà ara mìíràn sọ̀rọ̀. Ọ̀nà yòówù tí ó lè jẹ́, à ń sọ̀rọ̀ láti fi èrò inú ẹni han ẹlòmíràn ni.

Bí a bá ṣe àtúpalẹ̀ ohun tí a pè ní èdè ní òkè yìí, a ó ṣe àkíyèsí pé ènìyàn ni Olódùmarè jogún èdè fún kì í ṣe ohun ẹlẹ́mìí yòókù tí ó dá. A lè wòye pé àwọn ẹranko náà ní ọ̀nà tí wọ́n ń gbà láti bá ara wọn sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ náà sì ni àwọn ẹyẹ àti ohun abẹ̀mí yòókù bí ẹja. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí àgbébọ̀ adìẹ tí ó ń kó ọmọ rẹ̀ jẹ̀ kiri bá rí àṣá ní ojú òfurufú, ó ní irú ìró tí yóò mú jáde tí àwọn ọmọ wọ̀nyi yóò sí sá àsálà fún ẹ̀mí wọn, bẹ́ẹ̀ sì ni bí ó bá rí óunjẹ tí ó sì fẹ́ pe àwọn ọmọ rẹ̀, ó ní irú ìró tí yóò mú jáde tí àwọn ọmọ yóò sì sáré sí ọ̀dọ̀ rẹ̀. Ṣé a lè sọ pé èyí kì í ṣe èdè?.

Síwájú sí i, nígbà tí àwọn ààyá tàbí ọ̀bọ bá ya lu oko àgbàdo wọn a sáábà máa fi ọ̀kan nínú wọn ṣe alamí láti ta àwọn yòókù ní olobó bí ewu bá wà ní ìtòsí kí wọ́n ba à lè du ẹ̀mí wọn. Ohun tí àwọn ọ̀bọ wọ̀nyí sì ń ṣe ni pé wọn yóò jẹ àgbàdo tí wọn



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

yóò jẹ́ nígbà tí wọn yóò ya ti èyí tí ó ń ṣọ̀nà sílẹ̀ fún un. Bí ó bá jẹ́ wí pé èyí tí ó ń ṣọ́ ọ̀nà bá kẹ́fín pé ènìyàn ń bọ̀, ó ní irú ìró tí yóò mú jáde tí àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yóò sì bẹ́ sórí igi láti fi ẹsẹ̀ fẹ́ ẹ. Bí a bá wo ìṣe àwọn ẹranko wọ̀nyí, ṣé a lè gbà nítòótọ́ pé àwọn ẹranko kò ní èdè àti pé ènìyàn nìkan ni Ẹlẹ́dàá fi èdè jínkí?.

Àpẹẹrẹ mìíràn tí a ó yẹ̀wò ni tí ewúrẹ́ tí ó ń kó ọmọ kiri ṣùgbọ́n tí àwọn ọmọ náà jẹ̀ kúrò ní ọ̀dọ̀ ìyá wọn tàbí kí ìyá wá óunjẹ lọ tí kò sì rí àwọn ọmọ rẹ̀ ní ìtòsí. Ohun tí yóò kàn ni kí àwọn ọmọ ewúrẹ́ yìí máa pariwo láti pe ìyá wọn tàbí kí ìyá máa pariwo láti pe ọmọ rẹ̀. Ní ìgbà mìíràn, ó ṣeéṣe kí ó jẹ́ wí pé ewúrẹ́ tí ó bí ọmọ pọ̀ ní àdúgbò kí àwọn tí ó sì ń wá ọmọ wọn ju ẹyọ kan lọ, pàápàá jùlọ ní ìgbà tí òjò bá ṣú tàbí ilẹ̀ ń ṣú. Àkíyèsí fihàn pé nígbà tí ìyá tàbí ọmọ ewúrẹ́ ń ké yìí, àwọn ọmọ ewúrẹ́ yìí kì í ṣi ọ̀nà ọ̀dọ̀ ìyá wọn nítorí pé wọ́n dá ohùn rẹ̀ mọ̀, bí ìyá wọn ti ń ké náà ni àwọn ọmọ ń dáhún. Nígbà tí èyí rí bẹ́ẹ̀, ṣé a lè gbà pé ohun abẹ̀mí yòókù kò ní èdè àfi ènìyàn nìkan?.

Àlàyé tí a lè ṣe lórí àkíyèsí àti ìró àwọn ẹranko wọ̀nyí ni wí pé wọn kò ní èdè bí kò ṣe àmì àti ìró lásán èyí tí kò lè yípadà. Gbogbo àpẹẹrẹ tí a mú wá lórí àwọn ẹranko mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí jẹ́ àmì lásán nítorí pé àwọn àmì wọ̀nyẹn kò yí padá láàrin irúfẹ́ àwọn ẹranko wọ̀nyí.

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní ẹ̀rín kò yàtọ̀ títí dé ilú Òyìnbó, irú ìró tí adìẹ ilẹ̀ Yorùbá ń mú jáde nígbà tí ó bá rí ewu tí ó sì fẹ́ kí àwọn ọmọ rẹ̀ sá àsálà fún ẹ̀mí wọn náà ni adìẹ ní ilẹ̀ Háúsá tàbí Ìgbò tàbí Kànúrì tàbí ní Orílẹ̀-èdè mìíràn náà yóò mú jáde. Bákan náà ni ọmọ ṣe orí sì ni ọ̀rọ̀ yìí ní ọ̀dọ̀ àwọn ẹranko yòókù. Bí ajá òyìnbó ṣe ń gbó náà ni ti Yorùbá ń gbó, bí ológbò Yorùbá ṣe ń dún náà ni ti ilẹ̀ Faransé ń dún. Ohun mìíràn tí ó tílẹ̀ wà pẹ̀lú ìró àwọn ẹranko wọ̀nyí ni wí pé àdámọ́ ni ìró wọn kì í ṣe pé wọ́n kọ́ ọ nígbà tí wọn dé ilé ayé. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí ọmọ ajá ṣe ń gbó náà ni ìyá rẹ̀ yóò ṣe gbó, kò sí ìyàtọ̀ kankan níbẹ̀ bẹ́ẹ̀ sì ni wọn kò lè yí ohùn yìí padà láéláé. Fún ìdí èyí, ìró tàbí ariwo lásán ni àwọn ẹranko tàbí ohun abẹ̀mí yòókù léyìn ènìyàn ní, kì í ṣe èdè rárá.

Àlàyé mìíràn tí a lè ṣe lórí oríkì tí a fún èdè lókè ni pé ó hàn gbangba pé èdè kan náà kọ́ ni gbogbo ènìyàn ń sọ àti pé léyìn ìfìmọ̀ṣọ̀kan tàbí àdéhùn lórí ọ̀kan-ò-jọ̀kan orúkọ tí wọn ó máa pè ohun tí ó wà ní àyíká wọn àti àwọn ìṣe mìíràn ni àwọn ènìyàn ní agbègbè kọ̀ọ̀kan ń sọ èdè kan náà. Èyí kò wá yà wá lẹ́nu pé a ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè ní orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan ní àgbáyé lóníí. Bí a ti rí èdè Yorùbá ni a ní Haúsá, Ìgbò, Efik, Kànúrì, Urhobo, Ẹdó, Gẹ̀ẹ́sì, Faransé, Potogí, Látìní àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èdè yìí kì í ṣe

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ohun àmútọ̀runwá, ayé ni a ti ń kọ́ ọ. Èyí túmọ̀ sí pé ó ṣeéṣe fún ẹyọ ẹnikan láti gbọ́ àti láti mọ̀ ju ẹyọ èdè kan lọ.

## ÀBÙDÁ ÀDÁNI ÈDÈ

Nínú àlàyé tí a ṣe ní òkè, a tí rí àrídájú pé ènìyàn nìkan ni Olódùmarè jogún èdè fún. Fún ìdí èyí, a le pe èdè ní ogún àwùjọ ènìyàn. Kò sí ohun yòókù tí Ẹlẹ́dàá dá tí ó ní èdè bíkòṣe àmì lásán èyí tí kì í yípadà.

Àbùdá àdáni èdè mìíràn ni wí pé òun ni ó ń ya ènìyàn kan sọ́tọ̀ sí èkejì ó sì jẹ́ okùn tí ó so ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan pọ̀. Fún àpẹẹrẹ, bí a bá ti gbọ́ èdè Yorùbá ní ẹnu ẹnikan, wéré ni a ó ti mọ̀ pé ẹ̀yà Yorùbá ni bẹ́ẹ̀ sì ni tí ó bá jẹ́ èdè Haúsá tàbí Ìgbò èyí tí yóò mú wa mọ irú ẹyẹ tí ó ṣu ẹni bẹ́ẹ̀ nítorí pé kò sí ẹni tí ó jábọ láti ọ̀run tàbí ẹdá alààyè tí kò ní èdè tirẹ̀. Èdè yìí ni ó ń mú kí àjọṣepọ̀ tí ó dánmọ́rán wà láàrin ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ó sì jẹ́ okùn ọmọ ìyá nígbà ti elédè kan náà méjì bá pàdé ní ilẹ̀ àjòjì. Nígbà tí elédè kan náà méjì bá pàdé yìí, inú wọn yóò dùn wọn yóò sì rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ìyá kan naà èyí tí yoò mu kí wọ́n fi inu han ara wọn àti kí wọn sì dá ẹgbẹ́ ọmọ ìlú sílẹ̀ sí ilẹ̀ àjèjì.

Síwajú sí i, èdè jẹ́ ohun tí a fi ń ronú tí a sì fi ń fi èrò inú wa hàn fun ẹlòmíràn yàlà nípà sísọ ọ́ jádé lẹ́nú tàbí kíkọ ọ́ sílẹ̀. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ẹnu ẹni ni a fi ń sọ mi ò jẹ' èyí tí ó fihàn pé ohun tí a rò nínú wa ni a fi èdè gbé jáde, yàlà ó wù wá ni o tàbi kò wù wá. Bákan náà, èdè abínibí ni a fi ń ronu, òun ní a fi ń tumọ nǹkan, òun ni a fi ń lálàá tí a sì fi ń ṣe ohun gbogbo èyí tí ó fi ipò ńlá tí èdè wà sí ènìyàn hàn

Ọ̀nà tí à ń gbà láti fi èrò inú wa yìí hàn kò tún ṣẹ̀yìn èdè rárá, irú èdè yòówù tí ènìyàn lè lò. Nígbà tí inú ẹni bá dùn tí a sì fẹ́ fi èyí hàn, àǹfààní wà fún wa yálà láti kọ ọ́ sínú ìwé ìwé tàbí kí á sọ ọ́ lẹ́nu bẹ́ẹ̀ náà sì ni bí inú ẹni bá bàjẹ́. Èdè yìí ni a fi ń so bí nǹkan bá ń ṣe ènìyàn bí àarẹ̀, òun ni a fi ń sọ nípà ìṣòro yòówù ti ó lè dé bá ni àti ohun tí a bá ní lọkàn. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí a ó ti ṣe ni ààwí, ẹnìkàn kì í yan àna rẹ̀ lódì ṣíse yìí dá lórí ìlò èdè kì í sì í ṣe ohun mìíràn.

Àbùdá àdáni èdè mìíràn ni wí pé èdè ni a fí ń ṣe àlàyé ara wa. Níwọ̀n ìgbà tí a ní àwọn ọ̀nà mìíràn tí á ń gbà bá ara wa sọ̀rọ̀ láìlo ọ̀rọ̀ ẹnu tàbí èdè, ìgbà mìíràn wà tí àṣìṣe lè wà nínú ìtúmọ̀ tí a fún irúfẹ́ àmí báyìí nígbà tí èyí bá sì rí bẹ́ẹ̀, ohun tí ó kù ni kí á fi èdè gbé èrò ọkàn wa kalẹ̀. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní 'ebi ń pa mí kò ṣe é fi ìfé wí' bí ènìyàn ba ń fi ìfé wí èyí, kò sí ẹ̀rí pe ebi ń pa onítọ̀hùn àfi ìgbà tí ó bá fi ẹnu ara rẹ̀ wí i.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Nìgbà mìírán, a máa ń lo àwọn ẹ̀yà ara wa bí ẹ̀jìká síso, ojú ṣíṣẹ́ imú yíyín tàbí ohun èlò tí ó ní ìró bi ìlù, fèrè àti agogo láti fi pa àrokò ṣùgbọ́n ìṣòro àtimọ ìtumọ̀ ohun tí ẹni tí ó pa àrokò yìí ní lọ́kàn máa ń wáyé nígbàmíràn èyí tí yóò mú kí ẹni tí ó pa àrokò náà lo èdè láti fi ṣe àlàyé ara rẹ̀.

Kò pin sí ibí yìí, à ń fi èdè mọ̀ irú ẹni tí ẹnikan jẹ́. Èdè síso ni yóò jẹ́ kí á mọ̀ bóyá ọlọgbọ́n ni ẹnìkan tàbí òmùgọ̀, òun ni yóò jẹ́ kí á mọ̀ pé wèrè ni ẹlòmíràn. Nínú àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ ni a ti ń mọ̀ bóyá ènìyàn ní ìlàákàyè tàbí ó kù díẹ̀ káàtó fún un, nínú ìlò èdè ènìyàn ni a ti ń mọ̀ bóyà ilé ọgbọ́n ni a ti bí ènìyàn kan tàbí ọmọ-lọ-ilé-kí-a lọ-mú-èsì wá ni. Ní pàtó, èdè ni atọ́kùn èrò àti atọ́ka irú ẹni tí ẹnikan jẹ́.

Àbùdá àdáni mìíran tí èdè ní ni wí pé òun ni a fi fún gbogbo ohun tí ó wà ní àyíká wa ní orúkọ, orukọ, tí ó sì wù ẹ̀yà kọ̀ọ̀kàn ni ó fún ohun ti ó wà ní àyíká rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, lẹ́yìn ìfẹnuko ni Yorùba pe ẹ̀yà ara tí a fi ń gbé nǹkan tàbí mú oúnjẹ sí ẹnu ní 'ọwọ́' tí wọ́n sì ń pe ibi tí ènìyàn ń gbé ní 'ilé' tàbí 'house' ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti 'gida' ni èdè Haúsá. Kò sí ohun tí ó burú bí a bá pé ibi tí ènìyàn ń gbé ní 'ọwọ́ tí a sì pe ẹ̀yà ara tí a fi ń fi oúnjẹ sí ẹnu ní 'ilé' ṣùgbọ́n ohun tí ó ṣelẹ̀ tí a fi rí ọ̀kan-ò-jọ̀kan orúkọ ti à ń pe àwọn wọ̀nyí ni ìfìmọ̀ṣọ̀kan lórí orúkọ tí wọn yóò ma pè wọ́n.

## ÈDÈ ABÍNIBÍ

Lẹ́yìn tí a ti wo àbùdá àdáni ẹdá èdè, ó yẹ kí á mọ̀ nípa èdè abínibí. Èdè abínibí ni èdè tí ènìyàn gbọ́njú bá tàbí èdè àyíká ọmọdé nígbà tí ó bá fẹ́ kọ́ ọ̀rọ̀ síso. Èyí wà lọ́wọ́ agbègbè tí ọmọdé bá ti bá ara rẹ̀ láìka irú ẹ̀yà tí ó jẹ́ sí, ó sì fihàn pé kí í ṣe gbogbo ìgbà ni ó máa ń jẹ́ èdè tí wọ́n ń sọ ní ibi tí a ti bí àwọn òbí ẹni ni èdè abínibí ẹni.

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ó ṣeéṣe kí òbí ọmọ jẹ́ Ìgbò tàbí Ìdomà kí wọ́n wá máa gbé ní ilẹ̀ Yorùbá. Nígbà tí wọ́n bá bí ọmọ tí ọmọ náà sì ń dàgbà, yóò máa bá àwọn ọmọ Yorùbá tí ó wà ní agbègbè rẹ̀ ṣeré èyí sì ni yóò fún un ní àǹfààní láti gbọ́, láti mọ̀ àti láti sọ èdè Ìgbò tàbí Ìdomà sí i ní ilé nítorí pé wọn kò fẹ́ kí ó gbàgbé èdè rẹ̀, síbẹ̀, èdè agbègbè ọmọ yìí, èyí tí àwọn yóòkù ń sọ tí wọ́n fi ń ṣe ohun gbogbo ni òun náà yóò máa lò gẹ́gẹ́ bí ara wọn.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àríyànjiyàn ní ó ti wáyé tí ó sì tún ń wáyé lónìí láàrin àwọn onímọ̀ èdè lórí ohun tí èdè abínibí jẹ́. Nígbà tí àwọn mìíràn gbà wí pé èdè òbí ọmọ ni èdè abínibí rẹ̀ àwọn mìíran gbà wí pé èdè àdùgbò tí irú ọmọ náà dàgbà sí ni ó jẹ́ èdè abínibí rẹ̀. Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ wí pé kíkọ́ ni ènìyàn ń kọ́ èdè ní ìgbà tí àkókò bá

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

tó, èdè tí àwọn ará àdúgbò ibi tí ọmọ ń gbé ń sọ ni ó jẹ́ èdè abínibí rẹ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ọmọ náà kò lè dá gbé láìsí èdè, kò lè gbé èrò inú rẹ̀ jáde láìlo èdè bẹ́ẹ̀ ni kò lè mọ èrò àwọn aládùúgbò rẹ̀ bí kò bá gbọ́ tàbí mọ èdè wọn. Èdè àdúgbò yìí ni yóò ràn án lọ́wọ́ láti jẹ́ kí òun náà jẹ́ ọmọ àwùjọ náà.

Wàyí o, èdè abínibí ẹni a máa ní oríṣiríṣi àwòmọ́ tàbí ìrísí èyí tí a fi máa ń dá a mọ̀ yàtọ̀ láàrin àwọn èdè mìíran tí ó wù kí ẹni náà máa sọ. Ọ̀kan lára ìrísí yìí ni pé èdè abínibí ẹni ni ènìyàn máa ń gbọ́ jù. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí a bá bí ọmọ Yorùbá sí ilẹ̀ Haúsá tí ó sì dàgbà sí ibẹ̀ kí ó tó wá sí ilé, kò sí àní-àní pé èdè Haúsa ni ọmọ yìí yóò gbọ́ jù yóò sì rọ̀ ọ́ lọ́rùn láti sọ ju èdè Yorùbá lọ nítorí pé èdè tí ó ti mọ́ ọn lára tí ó sì fi ń gbé pọ̀ pẹ̀lú àwọn Haúsa láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni.

Ìrísí mìíràn pẹ̀lú èdè abínibí ni pé òun ni èdè tí àwọn tí ó yí ènìyàn ká máa ń sọ. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé èdè abínibí yìí ni a máa ń gbọ́ jù, kí á tó lè gbọ́ ọ dáadáa, a níláti máa rí ènìyàn sọ ọ́ sí kí á sì mọ ìtumọ̀-tẹ̀dọ̀ èdè náà. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ wí pé èdè abínibí ẹni ni àwọn tí ó bá yí ni ká máa ń sọ. Bí a bá ṣe àkíyèsí pé nígbà tí ènìyàn kan bá kúrò ní àdúgbò èdè abínibí rẹ̀ lọ sí àdúgbò mìíràn fún ìgbà pípẹ́ ó máa ń tó ọjọ́ díẹ̀ kí ó tún tó lè gbọ́ èdè abínibí yìí padà nígbà tí ó bá padà dé. Àpẹẹrẹ irú èyí ni àwọn ọmọ Nàìjíríà, pàápàá jùlọ àwọn ọmọ Ògbómọ̀ṣọ́ tí ìjọba ilẹ̀ Ghana lé wá sílé ní ọdún 1969 èyí tí ó fihàn pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ kò tilẹ̀ mọ ilé mọ́ dé ibi pé yóò gbọ́ èdè abínibí rẹ̀.

Síwájú sí i, èdè abínibí ẹni ni a fi lè ṣàlàyé ara ẹni jù. Nítorí pé èdè abínibí ẹni ni a máa ń gbọ́ jù, ó rọrùn láti fi ṣàlàyé èrò ọkàn wa ju èdè mìíràn tí a kọ́ lọ. Kò sí bí ènìyàn ti lè kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí Faransé gẹ́gẹ́ bí èdè kejì kí ó sì mọ̀ ọ́n sọ tó tí ó lè dàbí pé kí ó fi èdè abínbibí rẹ̀ ṣàlàyé ohun tí ó wà lọ́kàn rẹ̀. Ẹwẹ̀, nígbà tí a bá tilẹ̀ ń ṣe àlàyé ọ̀rọ̀ ní èdè kejì ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ìwádìí fihàn pé èdè abínibí ẹni ni a fi ń rò ó (Awóníyì, 1978).

Ohun mìíràn tí ó jẹ́ àwòmọ́ èdè abínibí ẹni ni pé a kì í kọ́ ọ bíkòṣe pé a kàn ń sọ ọ́ lẹ́nu a sì fi ń ronú ní àìròtẹ́lẹ̀. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú èdè kejì tàbí èdè mìíràn tí ènìyàn kọ́ nítorí pé kíkọ́ ni a máa ń kọ́ èdè kejì yìí. Fún ìdí èyí, ó rọrùn láti ṣe àlàyé ohun kan ní èdè abínibí ẹni ju èdè mìíràn lọ.

Àyẹ̀wò èdè abínibí yìí fihàn pé èdè tí a lè lò láti mú ìlọsíwájú wà ní àwùjọ̀ ni ó sí jẹ́ èdè tí a fi ń ronú. Èyí ni ó fà á tí a fi rí i pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀-èdè ní òde òní ni ó ń fi èdè abínibí wọn kọ́ ọmọ ní ilé-ìwé láti ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ títí dé ilé ìwé gíga èyí sì mú kí ìfẹ́ sí ẹ̀kọ́ ní àwọn orílẹ̀-èdè yìí gbòòrò sí i.

Ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ẹwẹ̀, kò tí ì sí ìfẹnukò lórí èwo nínú àwọn èdè abínibí ilẹ̀

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Nàìjíríà mẹ́ta tí ó ṣe pàtàkì jùlọ ni a lè yàn láàyò láti máa fi kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ẹ̀kọ́. Nínú ètò ẹ̀kọ́ titun onípele mẹ́rin tí à ń tẹ̀lé lónìí, èdè abínibí akẹ́kọ̀ọ́ ni olùkọ́ gbọ́dọ̀ fi kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní gbogbo iṣẹ́ àyàfi èdè Gẹ̀ẹ́sì nílé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní ọdún mẹ́ta àkọ́kọ́ tí ó sì jẹ́ kàn-ń-pá fún akẹ́kọ̀ọ́ láti yege nínú rẹ̀ nínú ìdánwò àbájáde ọlọ́dun mẹ́ta àkọ́kọ́ ti girama kí ó tó lè tẹ̀ síwájú ní ìpele kejì.

## ÈDÈ YORÙBÁ

Ọ̀kan pàtàkì lára èdè orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni èdè Yorùbá jẹ́. Kí í ṣe èyí nìkan, a tún lè rí àwọn tí ó ń sọ èdè yí ní àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn ní apá Ìwọ̀-Oòrùn Áfíríkà àti ní ilẹ̀ aláwọ̀ funfun. A ó túbọ̀ ṣe àlàyé lórí èyí níwájú.

Ohun kan tí ó ṣeni ní kàyéèfi nípa èdè Yorùbá ni wí pé kò sí ẹni tí ó lè sọ pàtó ibi tí orúkọ náà ti ṣàn wá bí omi agbada, ọ̀pọ̀lọpọ̀ kàn gbìyànjú láti fi òye gbé ọ̀rọ̀ náà kí wọ́n sì sọ tiwọn ni.

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, Awóníyì (1978) gbàgbọ́ pé orúkọ tí àwọn àjòjì kan ronú láti fún àwọn ènìyàn tí ó ń sọ èdè yìí ni, àwọn mìíràn gbàgbọ́ pé 'Akú' ni à ń pe àwọn ènìyàn yìí láti ìgbà tí wọ́n ti ti oko ẹrú dé sí ilẹ̀ Sàró àti pé a fún wọn ní orúkọ yìí nítorí 'Ẹ kú...' tí ó máa ń bẹ̀rẹ̀ ìkíni wọn. Báyìí, àwọn mìíràn gbàgbọ́ pé àwọn Haúsá ni ó pilẹ̀ orúkọ tí àwọn Yorùbá ń jẹ́ báyìí nítorí àwọn ni wọ́n kọ́kọ́ pe ọkùnrin wọn ní 'Yaribawa' tí wọ́n sì ń pe àwọn obìnrin ní 'Yarabanci' àti pé ibí yìí lọ ni Yorùbá ti jáde.

Atótónu yòówù kí á ṣe lórí ibi tí èdè yìí ti yàn orúkọ, ìwádìí fihàn pé èdè Yorùbá kò dá wà lásán bíkòṣe pé ó ní ìbátan. A gbàgbọ́ pé èdè Yorùbá wá láti ara àkójọpọ̀ èdè tí à ń pè ní 'Kwa' èyí tí ó wá láti ara àkójọpọ̀ èdè tí à ń pè láti agbègbè Niger-Congo. Yàtọ̀ sí èdè Yorùbá, àwọn èdè mìíràn tí ó wá láti ara èdè yìí ni Jukun, Ga, Ewe, Fante, Birom àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní tòótọ́, bí a bá wo àwọn èdè wọ̀nyí, a ó rí i pé èdè olóhùn ni gbogbo wọn àti pé ìbáṣepọ̀ tí ó gúnmọ́ wà nínú pípè tàbí ohùn wọn èyí tí ó fihàn pé ẹbí ni wọ́n nítòótọ́.

Ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, èdè Yorùbá jẹ́ èdè tí à ń sọ jùlọ ní ìpínlẹ̀ méje àwọn ìpínlẹ̀ náà sì ni Èkó, Ògùn, Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Ondó, Èkìtì àti Kúárà. Ẹwẹ̀, èdè yìí tún jẹ́ ọ̀kan lára èdè tí à sọ ní apákan ìpínlẹ̀ Ẹdó àti Kogí. Ọ̀kan lára èdè mẹ́ta tí ó ṣe pàtàkì ní ilẹ̀ Nàìjíríà lóde òní ni èdè Yorùbá jẹ́.

Yàtọ̀ sí ilẹ̀ Nàìjíríà, a tún ń sọ èdè Yorùbá ní àwọn orílẹ̀-èdè kan ní apá Ìwọ̀-Oòrùn Áfíríkà bí ilẹ̀ olómìnira Benin, Togo, Ghana ati Cote d'Voire nígbà tí a rí orílẹ̀-èdè mìíràn ní ìhà gúúsù orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà bí Cuba, Brazil, Haiti àti Trinidad tí a ti ń

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

sọ èdè Yorùbá. Ní gbogbo orílẹ̀-èdè tí a dárúkọ yàtọ̀ sí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, òwò ẹrú ni ó gbé àwọn ẹ̀yà Yorùbá dé ibẹ̀ ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ sì ni kò mọ ọ̀nà ilé wọn mọ́ lẹ́yìn tí òwò ẹrú dúró nígbà tí àwọn mìíràn fi àwọn orílẹ̀-èdè wọ̀nyí ṣe ilé nítorí pé ibẹ̀ ti mọ́ wọn lára. Ní báyìí tí àwọn ẹ̀yà Yorùbá ti wà káàkiri àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn, a kò gbọdọ̀ lérò pé bákan náà ni Yorùbá àwọn wọ̀nyí rí pẹ̀lú tí ilẹ̀ Nàìjíríà níbi tí àwọn ẹ̀yà yìí sodo sí, ìyàtọ̀ wà dáadáa láàrin wọn.

## YORÙBÁ ÀJÙMỌ̀LÒ

Níwọ̀n bí a ti ṣe àlàyé lókè pé èdè Yorùbá tí àwọn ẹ̀yà Yorùbá ń sọ káàkiri yàtọ̀ sí ara wọn, a lè bèèrè pé: báwo ni àwọn ẹ̀yà wọ̀nyí ṣe ń gbọ́ ara wọn àbí wọn kì í ní àjọṣepọ̀ ni? A ó ṣe àkíyèsí wí pé àwọn ènìyàn yìí rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ìyá èyí tí okùn àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin wọn yi danindanin. Nítorí ìgbàgbọ́ pé orírun kan náà ni àwọn ti wá, wọn a máa pe ara wọn ní 'ọmọ Odùduwà'.

Láìfi ti ìyàtọ̀ tàbí ìyapa tí ó wà láàrin èdè yìí ṣe, àwọn ọmọ Yorùbá ní Yorùbá kan tí wọ́n máa ń lò nígbà tí wọ́n bá pàdé ara wọn. Yorùbá yìí ni à ń pè ní Yorùbá àjùmọ̀lò. Ó jẹ́ èyí tí gbogbo Ọmọ Odùduwà gbọ́ tí wọ́n sì fi ń bá ara wọn sọ àsọyé nígbà tí wọ́n bá pàdé. Yorùbá àjùmọ̀lò yìí ni kì í jẹ́ kí á mọ̀ pé Ọ̀yọ́ ni Lagbájá ti wá, Èkìtì ni Tàmẹ̀dù ti wá tí Làkáṣègbè sí wá láti Ìjẹ̀bú. bí ọmọ ìlú ọ̀tọ̀ọ̀ tọ̀ bá pàdé, kálukú máa ń gbàgbé ìlú tí ó ti wá àti èdè ìlú rẹ̀ tí à ń pè ní ẹka èdè yóò sì máa sọ Yorùbá àjùmọ̀lò tí gbogbo wọ́n gbọ́.

A gbọ́dọ̀ mọ̀ wí pé kò sí èyí tí ó wúlò ju ara wọn lọ nínú àwọn ẹka èdè wọ̀nyí bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni ó máa ń sọ pé Yorùbá Ọ̀yọ́ ní à ń lò tàbí pé ó súnmọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ. Ohun tí ó ṣelẹ̀ ni wí pé púpọ̀ nínú àwọn tí ó ṣe àkọsílẹ̀ èdè Yorùbá bí Sámúẹ́lì Àjàyí Crowther ni ó súnmọ́ àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́ tí wọ́n sì gbé ìlànà kíkọ èdè Yorùbá sílẹ̀ pẹ̀lú Yorùbá Ọ̀yọ̀.

Yàtọ̀ sí èyí, ìwádìí fihàn pé Yorùbá Ọ̀yọ̀ ni o súnmọ́ èdè Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ nítorí pé òun nìkan ni àwọn ọ̀rọ̀ inú rẹ̀ kùn jùlọ tí ó sì rọrùn fún gbogbo ènìyàn láti mọ ìtumọ̀ rẹ̀. Èyí kò wá túmọ̀ sí pé Yorùbá Ọ̀yọ́ wúlò ju Yorùbá Èkìtì tàbí Yorùbá Ọ̀wọ̀ lọ bíkòṣe pé ẹka èdè ni gbogbo wọn. Yorùbá Ọ̀yọ́ ni lílò rẹ̀ gbòòro jù.

Yorùbá àjùmọ̀lò yìí ni à ń lò láti kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ìwe, tí à ń lò láti fi kọ ìwé èdè wà láàrin àwọn tí ó ń lo èdè náà àti pé ó ń mú kí wọ́n ka ara wọn sí ọ̀kan.



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**ÈKA ÈDÈ YORÙBÁ**

Nínú àlàyé wa lórí èdè Yorùbá ní òkè, a mọ̀ wí pé ìlú ilẹ̀ Yorùbá pọ̀ jántìrẹrẹ àti pé èdè Yorùbá tí ìlú kọ̀ọ̀kan ń sọ yàtọ̀ sí ara wọn. Èyí fihàn pé orísìírísìí ẹ̀yà ni Yorùbá pín sí. A lè mọ ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan nípa títẹ̀lé àwọn ìlànà yìí:

i) Agbègbè tàbí àdúgbò tí ó tẹ̀dó sí:

Níwọ̀n bí àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá kò ti wà ní ojú kan náà tí ó jẹ́ wí pé káàkiri tàn káàkiri ni ní ilẹ̀ Nàìjíríà, a lè tọ́ka sí agbègbè tí ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ń gbé láti mọ irú ẹ̀ka èdè tí wọ́n ń sọ. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ní Ìpínlẹ̀ Ògùn, a lè ṣe àkíyèsí pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá kan wà ní ilẹ̀ omi nígbà tí a ti lè rí àwọn Ìjẹ̀bú, àwọn kan wà ní ilẹ̀ igbó-Ẹ̀gbádò(Yewa) nígbà tí àwọn kan wà ní ilẹ̀ ọ̀dàn-Ẹ̀gbá. Ní Ìpínlẹ̀ Oǹdó bákan náà, a lè tọ́ka sí agbègbè tí àwọn ẹ̀yà Oǹdó, Àkúrẹ́, Ọ̀wọ̀ àti Ìdànrè ń gbé gẹ́gẹ́ bí ilẹ̀ ọ̀dàn nígbà tí a lè tọ́ka sí agbègbè àwọn Òkìtìpupa, Ọ̀de-Aye, Ìgbókọ̀dá, Arárọ̀mí àti Ayétòrò gẹ́gẹ́ bí ilẹ̀ omi. Ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ẹ̀wẹ̀, púpọ̀ nínú àwọn ìlú tí ó wà níbẹ̀ ni ó jẹ́ pé ilẹ̀ pápá ni wọ́n. Díẹ̀ lára àwọn ìlú náà ni Ọ̀yọ́, Ògbómọ̀ṣọ́, Ìṣẹ́yìn, Ìbàdàn àti Òkehò. Yàtọ̀ sí àwọn ìlú tí ó wà ní ilẹ̀ pápá yìí, a rí àwọn tí ó wà ní ilẹ̀ ọ̀dàn bí Àgó-Àrẹ, Tedé, Ìgbòho, Kíṣí àti Ṣakí.

ii) Irú ẹ̀yà Èdè abínibí tí wọ́n ń sọ:

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé a pín àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá nípa agbègbè tí wọ́n tẹ̀dó sí, síbẹ̀ a ó ṣe àkíyèsí wí pé èdè tí àwọn tí ó wà ní ìlú tí ó wà ní agbègbè kan náà ń sọ yàtọ̀. Fún àpẹẹrẹ, ẹ̀ka èdè Ẹ̀gbá ti Ìtokò yàtọ̀ sí ti Ìtẹsi, Ẹmẹ̀rẹ̀ yàtọ̀ sí ti Ìtòkú, ti Gbágùrá sì yàtọ̀ sí ti Ìlúgùn, síbẹ̀ ẹ̀ka èdè Ẹ̀gbá kan náà ni wọ́n ń sọ. Bákan náà ilẹ̀ igbó kan náà ni Iléṣà àti Ilé-Ifẹ̀ wà ṣùgbọ́n ẹ̀ka èdè wọn yàtọ̀ sí ara wọn.

iii) Iṣẹ́ tí ó wọ́pọ̀ láàrin wọn:

Èyí tún jẹ́ ọ̀nà kan tí à ń gbà láti mọ ẹ̀yà Yorùbá kan yàtọ̀ sí èkejì. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, iṣẹ́ aró dídá jẹ́ iṣẹ́ tí ó wọ́pọ̀ ní agbègbè Ọ̀ṣun àti Ẹ̀gbá, ẹní híhun wọ́pọ̀ ní agbègbè Ẹ̀gbádò, aṣọ híhun ni ti Ìṣẹ́yìn, igbá fífín àti ìlù sísè wọ́pọ̀ ní agbègbè Ọ̀yọ́ nígbà tí iṣẹ́ aró wọ́pọ̀ ní Ìsúndùn-únrín.

iv) Èsìn Ìbílẹ̀ èyí tí ó ṣe pé ní àárín ìlú kan ni ó ti múlẹ̀ jù:

Èyí tún jẹ́ ohun tí a fi lè dá ẹ̀yà Yorùbá kan mọ̀ sí èkejì. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ Ṣàngó ni òrìṣà tí àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́ gbé láruge jù, Ìṣẹ́yìn gbé Orò láruge, Oǹdó ni Ògún ṣọlẹ̀

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

sí, Agẹmọ jẹ́ ọba òrìṣà ní Ìjẹ̀bú, Ifá ni òrìṣà tí wọ́n káràmásìkí jù ní Ilé-Ifẹ̀ nígbà tí Ayélála jẹ́ òrìṣà tí ó gbilẹ̀ ní agbègbè Ìkálẹ̀ àti Ìlàjẹ.

v) **Oúnjẹ:**

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé kò sí oúnjẹ tí a lè sọ pé a kì í jẹ ní àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá síbẹ̀ agbabègbè kọ̀ọ̀kan ní ó ní oúnjẹ tí ó kúndùn jù èyí sì lè jẹ́ òdiwọ̀n láti mọ ẹ̀yà Yorùbá kan yàtọ̀ sí èkejì. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, a mọ èlùbọ́ láfún mọ ẹ̀yà Ẹ̀gbá, èlùbọ́ iṣu ni ti ẹ̀yà Ọ̀yọ́, iyán ti ni Ìjẹ̀ṣà àti Èkìtì nígbà tí àwọn Ìjẹ̀bú fẹ́ràn Ìkọ́kọrẹ́. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, Yorùbá gbà wí pé olórí oúnjẹ ni iyán àti atí pé amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ni àwọn oúnjẹ yòókù. Ìdí nìyí tí a fi máa ń gbọ́ ewì yìí lẹ́nu àwọn ọmọ ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀:

> Iyán loúnjẹ,
> Ọkà loògùn
> Àìrí rárá ni à ń jẹ̀kọ
> Kẹ́nù má dilẹ̀ ni gúgúrú.

Pẹ̀lú àlàyé lórí bi a ṣe ń dá ẹka èdè Yorùbá mọ̀ tí a ti ṣe ní òkè yìí, a lè pe ẹka èdè ní ọ̀nà tí ìró tàbí ọ̀rọ̀ gbà yàtọ̀ láti ìlú ilẹ̀ Yorùbá kan sí èkejì. Èyí ni kí ọ̀rọ̀ ní ìtumọ̀ kan náà kí pípè wọn yàtọ̀.

Ìró kì í ṣe bákan náà ní gbogbo èdè bẹ́ẹ̀ si ni ìro ohùn yàtọ̀ láti orílẹ̀-èdè kan sí òmíràn kò sì jọra láti èdè kan sí òmíràn èyí tí ó mú kí á ní ẹka èdè. Ẹka èdè ni ọ̀nà ìsọ̀rọ̀ ní ọ̀nà kan pàtó tí ó ń fi àwọn nǹkan tí ó yàtọ̀ hàn nípa bí a ti ń pe èdè tàbí sọ̀rọ̀ láti agbègbè kan dé òmíràn.

## ÌDÍ TÍ ẸKA ÈDÈ YORÙBÁ ṢE PÍN YẸ́LẸYẸ̀LẸ

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá yàtọ̀ sí ara wọn tí èdè ìlú kọ̀ọ̀kan náà sì yàtọ̀ sí ara wọn, ẹka èdè ni èdè ìlú kọ̀ọ̀kan yìí nítorí pé kò sí èyí tí ó kó ọ̀go já ní ti pé kí á máa dá òun nìkan lò nínú ìsọ̀rọ̀ tàbí ìkọ̀wé wa tí kò ní mú ìsòro wá níwọ̀n ìgbà tí gbogbo wa kò ti ti ìlú tàbí agbègbè kan náà wá. Yorùbá tí à lò yálà ní ilé ìwé, fún ìròyìn tàbí fún ìgbọ́ra-ẹni-yé ní ọjà tàbí ibòmíràn ni à ń pè ní Yorùbá àjùmọ̀lò.

Yorùbá àjùmọ̀lò yìí kì í ṣe ti ìlú tàbí ẹ̀yà Yorùbá kan gbòógì bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé àwọn mìíràn máa ń sọ pé Yorùbá Ọ̀yọ́ ni. Àkíyèsí fihàn pé kò sí ẹka èdè Yorùbá kan tí a mú fi ṣe Yorùbá àjùmọ̀lò, ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ni pé àkójọpọ̀ àwọn ẹka èdè Yorùbá ni ó di Yorùbá àjùmọ̀lò ṣùgbọ́n ẹka èdè Yorùbá Ọ̀yọ́ ni ó súnmọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jù. Síbẹ̀ ẹka èdè ni Yorùbá Ọ̀yọ́, Yorùbá Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ìyàlẹ́nu ni yóò jẹ́ pé bí gbogbo ìran Yorùbá ṣe jẹ́ Ọmọ Odùduwà tó nì tí a sì gbọ́ pé Ilé-Ifẹ̀ ni orírun gbogbo wa, ó ti ṣe wá jẹ́ tí gbogbo wa fọ́nká tí a kò sí ní ojú kan náà? Fífọ́nká yìí ni ó pàdí rẹ̀ tí a fi ní ẹ̀ka èdè Yorùbá tí ó pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ lóde òní.

Àlàyé tí a tún lè ṣe lórí àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí ó wà káàkiri ni pé ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ni ó dá dúró gẹ́gẹ́ bí ìlú ẹlòmíràn ni ayé àtijọ́ àfi Ọ̀yọ́ nìkan tí ó fi agbára àti ogun fa àwọn ìlú kan mọ́ra. Wọn kò mọ àwọn tí à ń pè'ní Yorùbá lónìí ní Yorùbá àwọn náà kìí sìí pe ara wọn bẹ́ẹ̀; ọ̀wọ́ Ọ̀yọ́ nìkan ni à ń pè ní Yorùbá tàbí ànàgó tàbí Yáríbáwá gẹ́gẹ́ bí àwọn Haúsá ti ń pè wọ́n (Ládélé, a.y. 1986).

Ohun àkọ́kọ́ tí ó mú kí ẹka èdè Yorùbá pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ ni ìjà sí ipò aṣíwájú àti ìjẹgàba tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọmọ Odùduwà ń jà lẹ́yìn ikú Odùduwà gẹ́gẹ́ bí ìtàn ṣe sọ. Nítòótọ́ ni pé ẹnìkan ni àkọ́bí ṣùgbọ́n níwọ̀n ìgbà tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọmọ wọ̀nyí ti mọ ara rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọba lọ́la, kálukú ni ó ń du ipò yìí. Ìjà àti ìfẹ́ àtijẹ ọba yìí ni ó mú kí àwọn ọmọ wọ̀nyí kúrò ní Ilé-Ifẹ̀ láti lọ tẹ ìlú dó. Nítorí ìdí èyí, a ń Olówu tí o lọ tẹ Òwu dó, Alákétu náà lọ tẹ Kétu dó, Ẹdó tẹ Ìbíní dó, Ọ̀ràngún tẹ Ìlá dó, Onísabẹ̀ẹ́ tẹ Sábẹ̀ẹ́ dó, Onípópó tẹ Pópó nígbà tí Ọ̀rànmíyàn tẹ Ọ̀yọ́ dó.

Ìṣípòpadà tí ó dé bá àwọn ènìyàn ní àkókò yìí mú kí ìyípadà dé bá èdè kan náà tí wọ́n ń sọ tẹ́lẹ̀ nítorí pé wọn yóò ṣe alábàápàdé àwọn nǹkan mìíràn tí kò sí ní agbègbè wọn tẹ́lẹ̀ bẹ́ẹ̀ sí ni ó ṣeéṣe kí wọn bá àwọn ènìyàn mìíràn tí èdè wọn yàtọ̀ pàdé, èdè àwọn méjèèjì yóò wọ inú ara wọn àwọn tí wọ́n sì jọ ń sọ èdè kan náà tẹ́lẹ̀ kò ní mọ̀ nípa àyípadà tí ìdàgbàsókè èdè tí ó ti wọ inú èdè kejì. A lè fi àwòrán ìsàlẹ̀ yìí ṣe àpèjúwe:




UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ohun mìíràn tí ó mú kí ẹ̀ka èdè Yorùbá pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ ni àjọṣepọ̀ nípa ìgbéyàwó. Ìgbéyàwó láàrin ẹya kan àti òmíràn ń mú kí àyálò ọ̀rọ̀ wayé tí ó sì lè mú kí ẹka èdè mìíràn jáde. Fún àpẹẹrẹ:

(1) àpótí - Ọ̀yọ́ (2) ipin - Ọyọ (3) ìkẹ̀tẹ́ - Ọ̀yọ́
òtìtà - Èkìtì ipẹn - Ẹ̀gbádò (Yewa) ẹkẹ́tẹ - Yewa
àtàpò - Ìjẹ̀bú (4) tún - Ọ̀yọ́ (5) ọ̀kan - Ọ̀yọ́
ìpèkù - Ẹ̀gbá tọ́n - Ọ̀ǹkò ọ̀kẹn - Ọ̀ǹkò
(6) èèyàn - Ọ̀yọ́
ònìàn - Yewa (Ẹ̀gbado)
ọ̀nìàn - Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì.

èyí tí ó ní ìtumọ̀ kan náà ṣùgbọ́n tí ìró wọn yàtọ̀, àjọṣepọ̀ nípa ìgbéyàwó lè mú kí ọ̀kan nínú àwọn orúkọ yìí wọ inú èdè kejì kí ó sì di ara èdè náà.

Yàtọ̀ sí àṣà ìgbéyàwó, ètò okòwò àti ìṣèlú tún jẹ́ pàtàkì ohun tí ó ń mú kí ẹka èdè Yorùbá pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ. Àjọṣepọ̀ okòwò ń fi ààyè sílẹ̀ fún ìlò ọ̀rọ̀ dáadáa nípa oríṣìíríṣìí orúkọ tí a fún àwọn ohun èlò tí a fi ń ṣòwò àti ìṣirò owó pẹ̀lú. Bákan náà ni ètò ìṣèlú ń mú kí ìyapa wà nípa ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìwà àti ìṣesí àwọn aláṣẹ àti àwọn àtẹ̀lé wọn. Nígbà mìíràn, bí ìlú kan bá kó ìlú kejì lẹ́rú nípasẹ̀ ogun, ó di dandan kí ìlú tí a kó lẹ́rú fi ara mọ́ àṣà àti ìṣe ìlú tí ó kó wọn lẹ́rú èyí tí yóò mú kí wọ́n máa sọ èdè mìíràn tàbí kí wọ́n yá ọ̀rọ̀ láti inú gbólóhùn kan wọ èkejì.

Síwájú sí i, ohun tí ó tún fà á tí ẹka èdè Yorùba ṣe pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ ni ti igbó ńlá tàbí odò tí ó pín àwọn ìlú sí méjì èyí tí ó sì fà á tí ìlú méjì báyìí kì í fi gbọ́ èdè ara wọn. Irúfẹ́ àwọn ènìyàn tí igbó ńlá tàbí odò ńlá bá gé kúrò lára àwọn ènìyàn wọn kì í ní àǹfààní láti bá ara wọn na ọjà tàbí ṣe àjọṣepọ̀ kankan mọ́. Fún àpẹẹrẹ Ìjẹ̀ṣà/Ifẹ̀; Òkè-Ògùn/Ọ̀yọ́; Ìbàràpá/Ẹ̀gbá; Ìkálẹ̀/Ìlàjẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìyàtọ̀ nínú ohun tí ó wà ní àyíká náà máa ń mú ìyàtọ̀ wà nínú orúkọ tí a fún àwọn nǹkan tí ó sì ń mú kí ìyàtọ̀ wà láàrin ẹka èdè kan sí èkejì. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àwọn ohun tí ó wà ní agbègbè omi àti igbó kìjikìji yóò yàtọ̀ sí ohun tí ó wa ní ilẹ̀ ọ̀dàn èyí yóò sì mú kí orúkọ àwọn nǹkan tí ó wà ní agbègbè kọ̀ọ̀kan yàtọ̀ sí ara wọn.

Àkíyèsí mìíràn tí a lè ṣe ni wí pé ó rọrùn láti tẹ̀dó sí ilẹ̀ ọ̀dàn ju ilẹ̀ igbó lọ nítorí àtipa ilẹ̀ kò sì ṣòro láti gé igi nítorí pé igi ńlá kò wọ́pọ̀ ní ilẹ̀ ọ̀dàn bí ilẹ̀ igbó èyí kò sì la wàhálà lọ danin-danin. Èyí ni ó fa sábàbí tí àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá Ọyọ́ ṣe pọ̀ tí wọ́n súnmọ́ ara wọn tí ẹka èdè wọn kò sì fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ara wọn bí ti àwọn tí ó wà ní ilẹ̀ igbó.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ÈYÀ YORÙBÁ

Ó yẹ kí á ṣe àlàyé ní ṣókí lórí àwọn ènìyàn tí à ń pè ní Yorùbá ní òde òní. Kò sí ẹni tí ó lè sọ pàtó ibi tí orúkọ yìí ti wá tàbí orísun ìtumọ̀ rẹ̀ ju wí pé ó jẹ́ orúkọ tí a lò fún àwọn ẹ̀yà ènìyàn kan tí èdè wọn wá láti ara èyí tí à ń pè ní 'Kwa' àti pé oríṣìíríṣìí orúkọ ni àwọn ẹ̀yà mìíràn ti kọ́kọ́ pè wọ́n bí "Akú", "Ulkami" tàbí "Alkamy" nígbà tí àwọn Haúsá ń pè wọ́n ní Yárìbáwá.

Ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà tí ó tóbi ní ilẹ̀ Nàìjíríà lóde òní a sì lè rí wọn ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ògùn, Èkó, Oǹdó, Èkìtì, Ọ̀ṣun àti Kúárà nígbà tí àwọn díẹ̀ wà ní ìpínlẹ̀ Ẹdó àti Kogí.

Yàtọ̀ sí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, a tún lè rí ẹ̀yà Yorùbá ní orílẹ̀-èdè bí Ghana, Benin, Togo, Sierra-Leone ati Cote d'Voire ní apá Ìwọ̀-Oòrùn Áfíríkà àti ní ilẹ̀ àwọn aláwọ̀ funfun bí Brazil, Cuba, Haiti àti Trinidad. Èyí fihàn pé ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí ó tóbi gan-an tí èdè wọn sì gbòòrò.

Ní ilẹ̀ Nàìjíríà, Adétúgbọ̀ (1982 : 211) pín àwọn Yorùbá sí ìpín mẹ́ta pàtàkì:

i) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (North West Yoruba = NWY)

Àwọn ìlú tí ó wà lábẹ́ ìpín yìí ni Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Igbó-Ọrà, Ìṣẹ́yìn, Ìlerò, Ẹdẹ, Ògbómọ̀ṣọ́, Òṣógbo, Ìkirè, Ìlaròó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

ii) Ààrin Gbùngùn Yorùbá (Central Yoruba = CY)

Ní abẹ́ ìpín yìí ni a ti rí ìlú bí Ìlá-Ọ̀ràngún, Iléṣà, Ìfàkì, Ìkálẹ̀, Ifọ́n, Adó-Èkìtì, Ilé-Ifẹ̀, Àkúrẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

iii) Gúúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (South East Yoruba = SEY)

Àwọn ìlú tí a rí lábẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Òkè-Ìgbó, Ilẹ̀-Olújìí, Ìdànrè, Oǹdó, Ìṣarà, Ìjẹ̀bú-Igbó, Òkìtìpupa, Ọ̀wọ̀, Ọ̀tà, Ìjẹ̀bú-Òde, Ìgbọ́kọ̀dá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Níwọ̀n ìgbà tí ojú ìwòye wa kò rí bákan náà àti nítorí pé ohun tí ó kọ ojú sí ẹni kan, èyìn ni ó kọ sí ẹlòmíràn, Oyèláràn (1976-1977 : 628 - 629) ní tirẹ̀ pín ẹ̀yà Yorùbá sí ìpín mẹ́rin pàtàkì. Àwọn ìpín náà ni:

A Yorùbá Ìwọ̀-Oòrùn (West Yoruba = WY)

(i) Ọ̀yọ́/Ìbàdàn/Ẹ̀gbá/Ọ̀họ̀rí - Ìfọ̀hìn

(ii) Òkè-Ògùn : A) Ṣakí, Ìjìó B) Kétu, Sábẹ̀ẹ́

(iii) Benin ati Togo

Ifẹ̀ (Togo), Idaisa, Manigri (Igue àti Yài, 1973)



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

B. Gúúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (South-East Yorùbá = SEY)
(i) Oǹdó, Ọ̀wọ̀
(ii) Ìjẹ̀bú
(iii) Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ̀

D. Àárín Gbùngùn Yorùbá (Central Yorùbá = CY)
Ilé-Ifẹ̀, Ìjẹ̀sà, Èkìtì.

E. Àríwá Ìlà-Oòrùn Yorùbá (North-Eastern Yorùbá = NEY)
(i) Ìgbómìná, Kakanda, Ìgbọ̀lọ̀
(ii) Jumu, Bunu, Oworo, Owe, Ẹ̀gbẹ̀.

## ÌYÀTỌ̀ LÁÀRIN YORÙBÁ ÀJÙMỌ̀LÒ ÀTI ÈKA ÈDÈ

Ìyàtọ̀ àkọ́kọ́ láàrin ẹka èdè àti Yorùbá àjùmọ̀lò ni a lè tọ́ka sí nípa àǹkóò fáwẹ̀lì. Èyí túmọ̀ sí pé nínú Yorùbá gbogbogbòò, a ní àwọn àdúgbò tí fáwẹ̀lì kan ti lè bá ara wọn rìn tí àwọn kan kò sì lè jùmọ̀ rìn. Fún àpẹẹrẹ, fáwẹ̀lì /u/ kì í bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní Yorùbá àjùmọ̀lò ṣùgbọ́n a rí ìlò rẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní àárin gbùngùn ilẹ̀ Yorùbá bí Iléṣà àti Èkìtì àti ní Oǹdó bí

| YORÙBÁ GBOGBOGBÒÒ | ILÉṢÀ | ÈKÌTÌ | OǸDÓ |
|---|---|---|---|
| Ilé | Ulé | Ulé | Ulí |
| Iṣu | Uṣu | Uṣu | Uṣu |
| Iyán | Uyán | Uyán | Uyán |
| Iléṣà | Uléṣà | Uléṣà | Ulíṣà |

Àǹkóò fáwẹ̀lì túmọ̀ sí pé àwọn fáwẹ̀lì máa ń jùmọ̀ kẹ́gbẹ́ nínú ìhun ọ̀rọ̀ Yorùbá ni kì í ṣe pé fáwẹ̀lì tí ó bá wu ènìyàn ni ó lè fi kún ẹyíkéyìí kọ́ńsónáńtì láti mú ọ̀rọ̀ tí ó ní ìtumọ̀ jáde. Òfin wà tí àwọn fáwẹ̀lì yìí ń tẹ̀lé kíwọ́n tó lè jùmọ̀ rìn. Fún àpẹẹrẹ, àwọn fáwẹ̀lì àyanudíẹ̀pè (ẹ àti ọ) kì í bá fáwẹ̀lì àhánùdíẹ̀pè (e ati o) rìn:

| | | |
|---|---|---|
| * ekọ | * ọfe | * ege |
| * ejọ̀ | * oje | * ọjo |

Èyí kò túmọ̀ sí pé àwọn fáwẹ̀lì tí ó jọ wà bákan náà kò lè bá ara wọn rìn nítorí náà, a lè rí fáwẹ̀lì àhánudíẹ̀pè tí ó ń bá ara wọn rìn bí epo, ejò, èfò, ẹ̀fọ́, ẹbọ, ẹ̀bẹ, òjé. òtẹ́

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

àti bẹ̀ẹ̀ bẹ̀ẹ̀ lọ. Yàtọ̀ sí fáwẹ́lì àhánudíẹ̀pè àti ayanudíẹ̀pè ti kì í bá ara wọ́n ṣiṣẹ́, fáwẹ́li ẹ̀bádò àti ẹ̀bákè kìí jẹyọ pọ̀ ninú ọ̀rọ̀ onísílébù méjì. Ìyàtọ̀ mìíràn láàrin Yorùbá àjùmọ̀lò àti ẹka èdè ni pé fáwẹ́li àìránmúpè méje ni ó wà nínú Yorùbá àjùmọ̀lò nígbà tí ti Ààrin Gbùngùn Yorùbá jẹ́ mẹ́sàn-án. Nínú fáwẹ́lì àránmúpè ẹ̀wẹ̀ tí a ti ní márùn-ún, méje ni ó wà ní ti Ààrin Gbùngùn Yorùbá èyí sì mú kí ìyàtọ̀ wà nínú ìhun ọ̀rọ̀ àti ìtumọ̀ wọn ní ìgbà mìíràn.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ kọ́ńsónáǹtì Yorùbá ni ó bá ara wọn mu ní ìpín mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a pín ẹ̀yà Yorùbá sí ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ kò ṣàìwà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ìlò /w/ ní Gúúsù Ìlà Oòrùn Yorùbá kò já gaara bí èyí tí wọ́n ń lò ní Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn. Ní Ààrin Gbùngùn Yorùbá, wọ́n ti já ìlò /w/ sílẹ̀ pátápátá èyí sì mú kí ìyàtọ̀ wà ní bí a ti ń pe ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan. Fún àpẹẹrẹ:

| ÀRÍWÁ ÌWỌ̀ OÒRÙN | GÚÚSÙ ÌLÀ OÒRÙN | ÀÀRIN GBÙNGÙN |
|---|---|---|
| o ó | oǒó | ó |
| Àwọ̀ | Àǒọ̀ | àọ̀ |
| Eéwo | oǒòo | eéo |
| Wẹ̀ | ọ̀ẹ̀ | ẹ̀ |

Síwájú sí i, ìyọ́pọ̀ tún jẹ́ ìyàtọ̀ mìíràn láàrin ẹka èdè àti Yorùbá àjùmọ̀lò. Nínú ẹka èdè, ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì máa ń wáyé ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà láti gbé ìtumọ̀ mìíràn jáde gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ nínú èdè Owoh Affar ní Ìkàrẹ́.

dá + ìwé = déwè

da + újù = doju

àkíyèsí fihàn pé fáwẹ́lì àkọ́kọ́ ni ó yọ́pọ̀ mọ́ èkejì láti mú fáwẹ́lì kẹta jáde.

Yàtọ̀ sí èyí, ìpajẹ tún jẹ́ ìyàtọ̀ pàtàkì mìíràn nínú ẹka èdè pàápàá jùlọ ìpajẹ ìro kọ́ńsónáǹtì èyí tí ó wọ́pọ̀ jù láàrin ẹ̀yà Ọ̀yọ́. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

Òtítà - Òòtà
ebíbú - ẹ̀ébú
ọ̀lẹ̀lẹ̀ - ọ̀ọ̀lẹ̀
àkàrà - àkàà
èkuru - ẹ̀kuu
èkùrọ́ - èkùọ́
èwìwọ̀ - èèwọ̀
ewúrẹ́ - eúrẹ́



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Àwọn kọ́ńsónáǹtì tí a máa ń sáábà pajẹ ni àwọn tí a gbà pé wọn kò lágbára tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ òkè yìí ti fihàn, a pa ìró kọ́ńsónáǹtì /t/, /b/, /l/, /r/ ati /w/ jẹ.

Ìpajẹ ìró fáwẹ́lì náà máa ń ṣẹlẹ̀ nínú ẹka èdè a sì lè tọ́ka sí àwọn àpẹẹrẹ yìí láti ẹka èdè Àárin Gbùngùn ilẹ̀ Yorùbá:

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| jẹ | + | usu | = | juṣu |
| mu | + | ọtín | = | mutín |
| sù | + | ùre | = | súre |
| jẹ | + | ùyà | = | jùyà. |

Ìyàtọ̀ mìíràn tí a tún lè rí láàrin Yorùbá àjùmọ̀lò àti ẹka èdè ni nípa àrànmọ́ èyí tí ó dá lórí síso àwọn fáwẹ́lì méjì tí ó wà ní fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ di irú ọ̀kan nínú fáwẹ́lì yìí. Fún àpẹẹrẹ:

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| ará | + | ìlú | = | aráàlú | ) | Yorùbá Àjùmọ̀lò |
| oní | + | ata | = | alátá | ) | |
| oní | + | owó | = | onówó | ) | Ẹka èdè Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. |
| oní | + | ata | = | onáta | ) | |

Kò pin sí ibí yìí, a ní àwọn ọ̀rọ̀ kan tí ó bá ara wọn mu, àwọn kọ́ńsónáǹtì wọn ṣe pàtàkì nítorí pé wọ́n jẹyọ ní àdúgbò kan náà. Àwọn kọ́ńsónáǹtì wọn yàtọ̀ ṣùgbọ́n àwọn fáwẹ́lì wọn bá ara wọn mu bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ìtumọ̀ kan náà ni wọ́n fún wa. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

| | | |
|---|---|---|
| awọ́nrínwọ́n | - | amọ́nímọ́ |
| yèrèpè | - | wèrèpè |
| pàkúté | - | tàkúté |
| dùn | - | yùn |
| fẹ́ | - | nẹ́ |

Ìmọ̀ wa nípa ìyàtọ̀ àti ìjọra tí ó wà láàrin ẹka èdè àti Yorùbá àjùmọ̀lò ń ràn wá lọ́wọ́ láti lè ṣe àtúpalẹ̀ àwọn lítíréṣọ̀ tí a kọ ní ẹka èdè kí á sì fún àwọn tí ó kọ ọ́ ní oríyìn.

Yàtọ̀ sí èyí, ó ń jẹ́ kí á ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn tí ó ń sọ àwọn èdè wọ̀nyí níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ wí pé a ti mọ orísìí èdè náà sọ a sì lè ní àǹfààní láti fi àwọn ẹka èdè yìí kọ ìwé.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## ATỌ́KA ÌYÍSỌ́DÍ NÍNÚ ẸKA ÈDÈ

Atọ́ka ìyísọ́dì ṣe pàtàkì nínú ṣíṣe àgbéyẹ̀wò ẹka èdè Yorùbá. Abẹ́ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ ìṣe ni ó wà nínú gbólóhùn. Àkíyèsí mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì ni pé atọ́ka ìyísọ́dì àti atọ́ka àsìkò wà ní agbègbè kan náà. Bí gbólóhùn kan bá fi àsìkò tí nǹkan yóò ṣẹlẹ̀ hàn ṣùgbọ́n tí nǹkan náà kò ṣẹlẹ̀ mọ́, atọ́ka ìyísọ́dì ni a ó fi yí i padà. Fún àpẹẹrẹ:

Wọ́n lọ - Wọn kò lọ.
Ìlú gbẹ́ kànga - Ìlú kò gbẹ́ kànga
Wọn yóò túúbá - Wọn kò ní túúbá.

Díẹ̀ lára ìyísọ́dì nínú èdè Yorùbá àjùmọlò àti ẹka èdè Yorùbá nìwọ̀nyí.

*** Kò, Kò ní, Kò kí ń
*** Kì
*** Kì í
*** Kè é, è é (Ìgbómìnà)
*** Rà a ) Ifẹ̀
*** Mẹ́ ẹ̀ )
*** À á, Kà á (Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Ọ̀gbómọ̀ṣọ́)
*** Ò - Olú ọ̀ wá.
*** Kí - Owó kí mo rí.
*** Kọ́, Kò - Aṣọ kọ́ ni mo rà
Àbákẹ́ kò lọ.

Nínú ẹka èdè, a lè wo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí fún ìmọ̀ kíkún sí i lórí atọ́ka ìyísọ́dì:

| S/N | ẸKA ÈDÈ | ATỌ́KA ÌYÍSỌ́DÌ | GBÓLÓHÙN |
|---|---|---|---|
| 1. | Ìkálẹ̀ | é è | Éè ṣèmi ó ṣé. |
| 2. | Èkìtì | èìí | Éìí ṣèmi ní ṣé. |
| 3. | Ìjẹ̀ṣà | é ràá | É ràá ṣèmi ló ṣe. |
| 4. | Ìjẹ̀bú | ééé | Ééé ṣèmi éé ṣé. |
| 5. | Ọ̀yọ́ | kìí | kìí ṣèmi ló ṣe é. |
| 6. | Yorùbá Àjùmọ̀lò | Kọ́ | Èmí kọ́ ni mo ṣe é. |

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

| | | | |
|---|---|---|---|
| Yorùbá àjùmọ̀lọ̀ | : | Kìí | Wọn kìí pariwo nibí o. |
| Ìdànrè | : | Mè ín | Ẹ mèín pario nibẹ́. |
| Ọ̀wọ̀ | : | Mèé | Ó mèé pariwo bé ó. |
| Àkúrẹ́ | : | Mè | Ọ́n mè pariwo bẹ́ẹ̀ líbéí o. |
| Ìjẹ̀bú | : | Mìí | Wọ́n mìí pariwo nibe o |

## ÌYÀTỌ̀ LÁÀRIN EKA ÈDÈ YORÙBÁ

Ní ìwọ̀n ìgbà tí a ti mọ̀ pé ìpín mẹ́ta pàtàkì ni a pín ẹ̀yà Yorùbá sí nípa eka èdè wọn tí a sì ti fihàn pé ìyàtọ̀ wà láàrin ẹka èdè yìí àti Yorùbá àjùmọ̀lọ̀, ó yẹ kí á mọ̀ wí pé ìyàtọ̀ tún wà láàrin àwọn ẹka èdè yìí. Ìyàtọ̀ tí ó wà ni a rí nínú àrin ìro tàbí bí a ṣe ń pe àwọn ìró Yorùbá ní ìpín mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.

Ní Gúúsù Ìlà Oòrùn bí Rẹ́mọ, Ondó, Ìkọ̀lé àti Ọ̀wọ̀, a ń lò /gh/ èyí tí ó jẹ́ èdè aṣorírun nínú ọ̀rọ̀ wọn bẹ́ẹ̀ ní Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn bí Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Òṣogbo àti Ògbómọ̀ṣọ́ /w/ ni wọ́n ń lò nígbà tí ó jẹ́ wí pé ní Àárin Gbùngùn bí Ifẹ̀, àti Ìjẹ̀ṣà ìpajẹ ti dé bá /w/ nítorí pé wọn kò lò ó mọ́. Fún àpẹẹrẹ:

| | GÚÚSÙ ÌLÀ -OÒRÙN | ÀRÍWÁ ÌWỌ̀-OÒRÙN | ÀÀRIN GBÙNGÙN | ÌTÚMỌ̀ |
|---|---|---|---|---|
| 1. | Ọghọ̀ | ọwọ̀ | ọ̀ọ̀ | ìgbálẹ̀(broom) |
| 2 | aghọn | awun | aun | ìjàpá (tortoise) |
| 3. | ghọn | wọn | ọn | wọn (they) |
| 4. | agho | awọ | a ọ | awọ ẹran (hide/leather) |
| 5. | èìghọ̀ | èèwọ̀ | èèọ̀ | èèwọ̀ (taboo) |
| 6. | ghọ̀ | wọ̀ | ọ̀ | (to look) |


Ìyapa mìíràn tí a tún rí tọ́ka sí láàrin ìpín mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni ìpó fónímù kọ́ńsónáǹtì Yorùbá /w/. Ní Gúúsù Ìlà Oòrùn /gw/ ni wọ́n ń lò ṣùgbọ́n ní Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn àti Àárin Gbùngùn /w/ ni wọ́n ń lò. Fún àpẹẹrẹ:

| | GÚÚSÙ ÌLÀ OÒRÙN | ÀRÍWÁ ÌWỌ̀ OÒRÙN | ÀÀRIN GBÙNGÙN |
|---|---|---|---|
| 1. | gwá | wá | wá (come) |
| 2. | gwọ́ | wọ́ | wọ́ (bend) |
| 3. | ìgwé | ìwé | ìwé (book) |
| 4. | àgwọn | àwọn | àwọn (they) |
| 5. | ààgwẹ̀ | ààwẹ̀ | ààwẹ̀ (fast) |




UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ìró fónńmù mìíràn tó tún máà ń yàtọ̀ sí ara díẹdíẹ̀ ni fáwẹ́lì.Méje ni fáwẹ́lì àìránmúpé ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè àmọ mẹ́sàn-án ni ó wà ní Ààrin gbùngùn ilẹ̀ Yorùbá (ní ẹ̀yà bí Èkìtì. Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà àti Àkúrẹ́). Àwọn fáwẹ́lì àìránmúpé mẹ́sàn-án náà nìyí:




Ní ti fáwẹ́lì àránmúpé, márùn-ùn ni ó wà ní àwọn ẹ̀yà tàbí ìpín Yorùbá yòókù ṣùgbọ́n méje ni ó wà ní Ààrin Gbùngùn Yorùbá. Àwọn náà ni:




Àpẹẹrẹ ìlò wọn nìyí:

1. /ũkɔ̃́/ ukọ́ (cough)
2. /ŨsΣ̃́/ uṣẹ́ (work)
3. /Ĩtã/ ìta (outside)
4. /Ũtà/ ujà (fight)
5. /ɔ̃dú/ ọdún (festival)

Bí àwọn fáwẹ́lì yìí ti ṣe pò tó yìí, ó lójú àwọn tí wọ́n lè jọ kẹ́gbẹ́ tàbí jùmọ̀rìn. Ọ̀nà méjì ni àwọn fáwẹ́lì àìránmúpè pín sí:

(i) Àwọn tí a máa ń fi agbára pè
(ii) Àwọn tí a kìí fi agbàra pè

| Àfagbárapè | | | Àìfagbárapè | |
|---|---|---|---|---|
| i | | u | I | U |
| e | s | o | E | O |

Fáwẹlì àfagbárapè máa ń jùmọ̀ rìn bẹ̀ẹ̀ sì ni fáwẹ́lì àìfagbárèpè náà máa ń jùmọ̀ rìn. Fáwẹ̀lì àfagbárapè kò lè kẹ́gbẹ́ pẹ̀lú fáwẹ́lì àìfa- gbárapè àfi fáwẹ̀lì /a/ àìfagbárapè tí ó lè jùmọ̀ rìn pẹ̀lú èyíkéyìí fáwẹ̀lì nínú ìsọ̀rí méjèèjì.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Àkíyèsí ìyàtọ̀ mìíràn tí a lè ṣe ni pé fáwẹ́lì /u/ kì í bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní Àríwá Ìwọ̀ Òòrùn Yorùbá ṣùgbọ́n Yorùbá Gúúsù Ìlà Oòrùn àti Àárin Gbùngùn gba èyí láyè. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

| | |
|---|---|
| Ulé | Ilé |
| Uyán | Iyán |
| Uṣu | Iṣu |
| Ùwọ̀ | Ìwọ̀ |

Àwọn fáwẹ́lì àránmúpè tí ó wà nínú ẹka èdè Yorùbá nìyí:

| ÀRÍWÁ ÌWỌ̀ OÒRÙN | GÚÚSÙ ÌLÀ OÒRÙN | ÀÀRIN GBÙNGÙN |
|---|---|---|
| Ĩ ũ | ĩ ũ | Ĩ Ũ |
| ɔ | Σ | Ĩ U |
| | ã | Σ ã ɔ |
| 3 | 5 | 7 |
| Àpẹẹrẹ ìlú : Ọ̀yọ́ Ìbàdàn, Ògbómọ̀ṣọ́ | Àpẹẹrẹ ìlú : Ọ̀wọ̀, Oǹdó, Ìjẹ̀bú-Òde | Àpẹẹrẹ ìlú : Iléṣà, Ifẹ̀ Èkìtì. |

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**Ìbéèrè Fún Ìdánrawò**

1. (a) Kí ni Èdè?
   (b) Kín ni àbùdá àdáni Èdè?
2. Ní èrò tìrẹ ǹjẹ́ o gbà pé àwọn ẹranko kò ní Èdè?
3. Ọ̀kàn náà ni gbogbo ọmọ Yorùbá láti òkè títí dé ìsàlẹ̀. Ǹjẹ́ o fi ara mọ́ gbólóhùn yìí?
4. Kí ni ìdí rẹ̀ tí ẹka èdè Yorùbá ṣe pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ?
5. Àwọn ìyàtọ̀ wo ni ó wà láàrin Yorùbá àjùmọ̀lọ̀ àti ẹka èdè Yorùbá.?
6. Ǹjẹ́ ìyàtọ̀ tìlẹ̀ wà láàrin àwọn ìpín ẹka èdè Yorùbá?.
7. Orísìírísìí aṣóka ìyísódì wo ni ó wà nínú ẹka èdè Yorùbá?
8. Kín ni àwọn ohun tí ó ya èdè Yorùbá kan sọ́tọ̀ sí èkejì?
9. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí bí a ṣe ń dá ẹ̀ka èdè Yorùbá mọ̀.

# ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adétúgbọ̀, Abíọ́dún (1982): "Towards a Yorùbá Dialectology" nínú Afọláyan A. (ed.) Yorùbá Language and Literature, Ìbàdàn/Ifẹ̀: University Press Limited & Unifẹ Press. o.i. 207 - 224.

Akínbọ̀, Rótìmí (1992): Èka Èdè Yorùbá (Ìwé Ìléwọ́), St. Andrew's College of Education, Ọ̀yọ́. August.

Awóníyì, T.A. (1978): Yorùbá Language in Education: (1846 - 1974). Ìbàdàn: Oxford University Press.

———— (1982): The Teaching of African Languages, London: Hodder and Stoughton.

Ládélé, T.A.A. (a.y) (1986) : Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá Lagos : Macmillan Nigeria Publishers Ltd., o.i. 1-12.

Mustapha, O. (a.y.) (1987) : Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá Titun, (J.S.S.) Ìwé Kejì Ìbàdàn : University Press Limited, o.i. 84 - 87.

———— (1991) : Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá Titun (SSS) Ìwé Kejì, Ìbàdàn : University Press PLC o.i. 1-7

Owólabí, O. (a.y.) (1985): Ìjìnlẹ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá, Ìwé kìn-ín -ní; Ibadan: Evans Brothers (Nigeria Publishers) Ltd. o.i. 5-6; 33-34.

Oyèláràn, O.O. (1976-1977): 'Linguistic Speculations On Yorùbá History' in Oyèláràn O.O. (ed) (1976) Seminar Series Number I Part II, University of Ifẹ̀.

Ọdúnjọ, J.F. (1976): Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá : Aláwìíyé fún Àwọn Ilé-Ẹ̀kọ́ Gíga, Apá Kìn-ín-ní, Ìkẹjà : Longman Nigeria Ltd., o.i. 3-9.

## ÌWÉ MÌRÀN FÚN ÀYẸ̀WÒ

Awóbùlúyì, O. (1992): 'Aspects of Contemporary Standard Yorùbá In Dialectological Perspective' in Ìṣọ̀lá, Akínwùmí (ed.) New Findings in Yorùbá Studies J.F. Ọdúnjọ Memorial Lecture Series No. 3 Department of Linguistics and African Languages U.I. Ibadan.

Bámgbóṣé, Ayọ̀ (1986) : Yorùbá : A Language in Transition. Ọdúnjọ Memorial Lecture Series.



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY